# مطوية أعمال الحج)للوزارة(

# Awọn iṣẹ ijọsin Hajj

## Awọn iṣẹ ijọsin Hajj

Muhammad ọmọ Solih Al-Uthaymīn

Orilẹ-ede Saudi Arebia

Ile-iṣẹ aṣoju ijọba l'ori awọn nkan ọrọ ẹsin Isilaamu ati ọrọ ipepe soju ọna Ọlọhun ati itọnisọna

## Àwọn iṣẹ́ ìjọsìn Hajj

Ti onipò giga, Sheikh:

Muhammad ọmọ Solih Al-Uthaymīn kọ

Kí Ọlọhun ba wa kẹ ẹ.

## Iṣẹ́ ọjọ́ àkọ́kọ́

## èyí tii se ọjọ́ kẹjọ

1- ( ẹni tí ó jẹ́ olùgbé Makkah àti àwọn agbègbè rẹ̀) Yóò gbé harami fún iṣẹ̀ ìjọsìn Hajj láti ibi tí ó wà, yóò wẹ̀, yóò lo lofinda, yóò sì wọ aṣọ harami, yóò sì wí pé:

Labbaika Hajjan, Labbaikal laahummo labbaik, labbaika laa sheriika laka labbaik, innal amda, wan ni'imata, laka wal mul'k, laa sheriika lak. Èyí ni o túmọ sí pé : motijẹ ìpe rẹ Ọlọhun fún ìjọsìn Hajj, Irẹ Ọlọhun moti jẹ ìpe rẹ lajẹunjẹ , kò sí orogún kan kan fún ọ , àní mo moti jẹpe , dájú dájú ọpẹ, idẹra àti ọlá tàbí ìkápá kòsí orogún kan kan fún Ní ti ẹni tí kò dé Makkah àfi ní ọjọ́ yí , tí ó sì ń bọ̀ láti ẹ̀yìn àwọn ààyè igbe harami, kò gbọdọ̀ kọjá ààyè harami láì gbé harami náà 2- Yóò gba muna lọ, yóò sì wà níbẹ̀ títí tí oòrùn yóò fi yọ ní aarọ ọjọ kẹsan-an, yóò sì kí Irun ọsán (Zhuri) ti ọjọ kẹjọ níbẹ̀, àti Irun irọlẹ (Asr) àti Irun aṣalẹ (Magrib) àti Irun Akisun (Ishai) àti irun ìdaji (Fajr) ti ọjọ kẹsan-an,

irun kọọkan ní àkókò rẹ̀, yóò sì máa se ẹdinku àwọn irun olopo mẹrin.

## Iṣẹ́ ìjọsìn ọjọ keji

## Tí ó jẹ́ ọjọ kẹsan

1- Yóò gbéra lọ sí Harafah lẹ́yìn tí oòrùn bá ti yọ, yóò sì ki irun aila àti alaasari ní ẹdinku àti ní akipọ̀ itisíwájú, yóò sì sọkalẹ – nígbàtí o bá dé – sí ààyè Namrah síwájú kí oòrùn tó yẹ kúrò ní àtàrí, tí o bá rọrùn fún un.

2- Yio fí asiko lẹ lẹyin irun fún ìrántí Ọlọ̣hun àti Adura, yóò dájú kọ ibudajukọ ni ẹni tí yóò gbé ọwọ rẹ mejeeji sókè títí oòrùn yóò fi wọ.

3- Yóò sí gbà Muzdalifah lọ lẹyin ìwọ̀ oòrùn, yóò sì kí irun Magrib níbẹ̀ ní rakah mẹta àti irun Ishai ní rakah méjì, yóò sì sun mọju níbẹ̀ títí ilẹ yóò fi mọn.

4- Yio ki Irun Fajri ( ìrun  aarọ ) lẹyin ti alfajiri ba ti yọ, lẹyin naa yio wa fi ara balẹ fun ṣiṣe Iranti Ọlọ̣hun ati Adua títí ilẹ yóò fi mọn daadaa.

5- Yóò sí gbà Mina lọ padà kí oòrùn tó yọ.

## Iṣẹ́ ìjọsìn ọjọ kẹta

## Ó sì jẹ́ ọjọ Ọdun

1- Tí ó bá dé Mínà, yóò lọ sí bi Jamratul Aqaba, yóò si ju ú okuta ni ààyè náà  pẹ̀lú òkúta kekeke méje ní tẹ̀lé-ǹ-tẹ̀lé ni ọ̀kọ̀ọ̀kan, tí yóò máa gbé Ọlọ̣hun tóbi pẹ̀lú juju òkúta kọ̀ọ̀kan.

2- Yóò pa ẹran adaaya rẹ̀ tí ó bá ní ẹran adaaya.

3- Yóò fa irun orí rẹ̀ tàbí kí ó gẹ́ẹ́, yóò sì fi ìyẹn ṣe ìtúsílẹ̀ àkọ́kọ́; yóò wọ aṣọ rẹ̀, yóò sì lo lọfinda, gbogbo àwọn ohun èèwọ̀ wiwa nínú harami yóò sì di ẹtọ fún un yàtọ̀ sí àwọn obìnrin.

4- Yóò bọ sí Makkah, yóò sì ṣe irọkirika Ilé Ọlọ́hun, Tawaaful Ifaadọ, òun sì ni irọkirika Hajj. Yóò sì ṣe ipọsẹṣẹ láàrin Sọfa àti Marwah fún Hajj, tí ó bá jẹ́ oní-tamattu', bákan náà bí kò bá jẹ́ oní-tamattu' tí kò sì tíì ṣe ipọsẹṣẹ pẹ̀lú Tawaaful-kuduum.

Bayii ni yoó bọra silẹ pátápátá ní ìgbà ẹlẹẹkeji, gbogbo àwọn ohun èèwọ̀ ìwọṣọ harami yóò sì di ẹtọ fún un, títí kan sunsunmọ àwọn obinrin.

5- Yóò padà sí Múná, yóò wa sun níbẹ ní alẹ ọjọ́ kọkànlá.

## Iṣẹ́ ọjọ́ kẹrin

## Ó sì jẹ́ ọjọ́ ẹlẹẹkọkanla

Yóò ju àwọn Jamarat mẹ́tẹ̀ẹ̀ta, àlakọ́kọ́, lẹ́yìn náà èyí tó wà láàrin, lẹ́yìn náà Jamratul Aqaba, ọ̀kọ̀ọ̀kan pẹ̀lú òkúta méje ní tẹ̀léǹtẹ̀lé, yóò máa gbé Ọlọ́hun tóbi pẹ̀lú òkúta kọ̀ọ̀kan. Yóò ju wọ́n lẹ́yìn tí oòrùn bá yatarí, kò sì yọ̀nda ṣáájú rẹ̀, a ó sì kíyèsí dídúró fún àdúà lẹ́yìn Jamrah àkọ́kọ́ àti èyí tó wà láàrin.

2- Yio máa sun mọju ni Mina ni alẹ ọjọ kejila.

## Iṣẹ́ ọjọ́ karùn-ún

## Tí ó jẹ́ ọjọ́ kejila

1- Yóò ju òkúta mẹtẹta náà gẹgẹ bí o se júù ni ọjọ kẹrin.

2- Yóò gbé ra láti Muna kí oòrùn tó wọ tí ó bá fẹ́ kánjú kúrò, tàbí kí ó sùn mọjú níbẹ̀ tí ó bá fẹ́ lọra láti lọ .

## Iṣẹ́ ìjọsìn ọjọ́ kẹfà, tí í ṣe ọjọ́ kẹtàlá

Ọjọ yii da wa lọtọ fún ẹni tí ó pẹ́, tí ó sì ṣe iṣẹ́ nínú rẹ̀:

1- Yóò sọ àwọn Jamarat mẹtẹẹta gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe é ní àwọn ọjọ́ méjì tí ó ṣáájú.

2- Yio gbera kuro ni Mina lẹ́yìn náà.

Ati pé iṣẹ igbẹyin ni irọkirika ti idagbere nígbàtí ó bá fẹ́ ṣe ìrìn-àjò, Ọlọhun lo ni imọ jùlọ.

# Index

Awọn iṣẹ ijọsin Hajj ........................................................ 2
Àwọn iṣẹ́ ìjọsìn Hajj ........................................................ 2
Iṣẹ́ ọjọ́ àkọ́kọ́........................................................ 2
èyí tii se ọjọ́ kẹjọ........................................................ 2
Iṣẹ́ ìjọsìn ọjọ keji........................................................ 3
Tí ó jẹ́ ọjọ kẹsan........................................................ 3
Iṣẹ́ ìjọsìn ọjọ kẹta........................................................ 3
Ó sì jẹ́ ọjọ Ọdun........................................................ 3
Iṣẹ́ ọjọ́ kẹrin ........................................................ 4
Ó sì jẹ́ ọjọ́ ẹlẹẹkọkanla........................................................ 4
Iṣẹ́ ọjọ́ karùn-ún ........................................................ 4
Tí ó jẹ́ ọjọ́ kejila........................................................ 4
Iṣẹ́ ìjọsìn ọjọ́ kẹfà, tí í ṣe ọjọ́ kẹtàlá ................................. 5

yo499v1.0 - 06/09/2026